## AWỌN Ọ̀RỌ IYANJU FUN AWỌN ONIGBAGBỌ́

## 1 Peteru 3:1-22;  4:1-19;  5:1-11.

## ẸKỌ 453  –  FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nitorina ẹ rẹ̀ ara nyin silẹ labẹ ọwọ́ agbara Ọlọrun, ki on ki o le gbé nyin ga li akokò" (1 Peteru 5:6).**

### Idena Adura

Awọn iwe ti a kọ lati ọwọ Peteru jẹ eyi ti a kọ si awọn Onigbagbọ. Onigbagbọ ni ẹni ti n tẹle Jesu ati awọn ẹkọ Rẹ̀. Onigbagbọ jẹ ẹni ti o gba Ọrọ Ọlọrun gbọ́, ti o si n ṣe ohun ti Bibeli kọ́ ni. "Ni Antioku li a si kọ́ pè awọn ọmọ-ẹhin" Jesu "ni Kristiani" (Iṣe Awọn Apọsteli 11:26).

Lẹyin igba ti eniyan ba ri igbala, o ni lati maa ba Oluwa rin, ki a ba le fi ounjẹ bọ́ ọkàn rẹ̀. O ni lati maa ka Bibeli ki o si maa gbadura ni ojoojumọ. Peteru tọka si awọn nnkan ti o le ṣe idena si idahunsi adura eniyan. Eniyan gbọdọ ṣọra nipa iru iwa ti o n hù ni ile loju awọn ẹbi ati ọrẹ rẹ̀ timọtimọ. Onigbagbọ́ tootọ maa n wà fun Jesu ni wakati gbogbo, ki i ṣe ile-isin nikan ṣugbọn ni ile, ni ile-ẹkọ, ni ibi iṣẹ tabi ibi iṣire. Pẹlu Jesu ninu ọkàn rẹ̀, oun yoo fẹ́ lati bọwọ fun ni, lati ni iyọ́nu ati lati fẹran ẹlomiran. Ẹni ti a fun ni ọkàn titun lati ọdọ Jesu a maa ṣe rere fun gbogbo eniyan, ati fun awọn ti ko huwa daradara si i pẹlu. Jesu kọ́ awọn eniyan Rẹ̀ ni Ofin Wura: "Nitorina gbogbo ohunkohun ti ẹnyin ba nfẹ ki enia ki o ṣe si nyin, bẹ̃ni ki ẹnyin ki o si ṣe si wọn gẹgẹ"(Matteu 7:12).

### Awọn Ọṣọ

Nigba pupọ ni awọn eniyan n fẹ fi ara hàn bi eniyan rere niwaju awọn ẹlomiran, wọn si n gbiyanju lati fi ohun ti o wa ninu ọkàn wọn gan an pamọ. Ipo ti ọkàn wà ṣe pataki ju ohun ti o bo ode-ara lọ. Eniyan le ni aṣọ daradara ati iwa ọmọluwabi, aago-ọwọ ati mọto olowo iyebiye, ṣugbọn Ọlọrun n wo kọja eyi ni lọ sinu ọkàn. Ni akoko Dafidi, Woli Samuẹli wi pe, "OLUWA ki iwò bi enia ti nwò; enia a ma wò oju, OLUWA a ma wò ọkàn"(1 Samuẹli 16:7).

Peteru kọ́ ni pe "ọ̀ṣọ́ aidibajẹ ti ẹmi irẹlẹ ati ẹmi tutù" ṣe iyebiye pupọ niwaju Ọlọrun. Eniyan ko ṣẹṣẹ ni lati sọ fun ni pe oun ni ọkan rere tabi pe oun ni ẹmi irẹlẹ ati ẹmi tutu. Awọn nnkan wọnyii n ti ọdọ Ọlọrun wá, wọn si n yi iwa ati iṣe eniyan pada. Nigba ti eniyan ba ri igbala, oun yoo ni ọkàn titun. Lẹyin naa bi o ti gbọran si Ọlọrun, ti o n gbadura ti o si n fi igbesi-ayé rẹ̀ rubọ fun Oluwa, oun yoo ri awọn oore-ọfẹ Onigbagbọ wọnyii gbà lati ọdọ Ọlọrun; oun yoo ni ọṣọ ti ẹmi; oun yoo ni eso ti Ẹmi (Galatia 5:22, 23). Onigbagbọ a maa wọṣọ gẹgẹ bi Onigbagbọ, ki i si ba wọn lọwọ ninu aṣa ayé. Awọn Onigbagbọ yàn lati dá yatọ si ero ayé, wọn si n gbiyanju lati fi ogo fun Ọlọrun lọna iwọṣọ wọn ati ninu ihuwasi wọn.

### Aabo

"Nitori oju Oluwa mbẹ lara awọn olododo, eti rẹ̀ si ṣi si ẹbẹ wọn: ṣugbọn oju Oluwa nwo awọn ti nṣe buburu". Wo bi o ti jẹ́ itunu to fun Onigbagbọ lati mọ̀ pe Ọlọrun n ri ohun gbogbo: ohun ti a n ṣe si i ati ohun ti oun naa n ṣe bakan naa! Wo bi o ti dara to fun un lati mọ pe oun le ke pe Ọlọrun ati wi pe eti Rẹ̀ ṣi si adura! Ni igba aini eniyan le ké fun iranwọ ṣugbọn ko ni idaniloju pe eniyan kan yoo gbọ́ tabi pe eniyan kan yoo tilẹ fẹ ṣe iranwọ. Wo iru ibukun ti o jẹ́ fun Onigbagbọ lati mọ̀ pe Ọlọrun n ṣọna O si n tẹti silẹ, O n duro lati daabo bo o ati lati ràn án lọwọ!

Ọlọrun ha mọ nipa awọn wọnni ti wọn ko ri igbala? Ninu Owe 15:3 a ka pe, "Oju OLUWA mbẹ ni ibi gbogbo, o nwò awọn ẹni-buburu ati ẹni-rere". Ọlọrun mọ ohun ti eniyan n ṣe -- awọn ẹni-rere ati ẹni-buburu -- ṣugbọn oju Rẹ̀ "nwò awọn ti nṣe buburu". Ronu itumọ ohun ti o jẹ́ lati ni ẹ̀ṣẹ ati ibi ninu ọkàn eniyan. Oju Ọlọrun kan si iru awọn eniyan bẹẹ, wọn ki yoo si ni alaafia tootọ titi wọn yoo fi ni iyipada ọkàn, ẹ̀ṣẹ wọn a si kuro. Ọlọrun le ri ọkàn rẹ; si ranti pe, a n ṣọ ọ. A le ri eyi gbangba pe o ṣafaani lati sin Jesu ki a si ni iranwọ ati aabo Rẹ̀.

**Ireti**

Lẹyin gbogbo nnkan wọnyii, Onigbagbọ ni ireti nla kan – pe Jesu yoo wà pẹlu Oun, pe Jesu yoo ran oun lọwọ, pe Jesu yoo pa oun mọ́, ati pe Jesu yoo mu oun lọ si Ọrun. A ti kọ́ ninu Bibeli pe,"nipa sũru ati itunu iwe-mimọ́ ki a le ni ireti" (Romu 15:4). Ireti jẹ idakọro ọkàn (Heberu 6:19). O si n mi si ni lati jẹ́ mimọ́ (1 Johannu 3:3). "Iwọ ṣe ireti niti Ọlọrun" (Orin Dafidi 42:11).

Peteru ni ki Onigbagbọ "mura tan nigbagbogbo lati dá olukuluku lohùn ti mbere …… ireti ti o mbẹ ninu" rẹ̀. Wọn le beere nigba miiran lọwọ ẹni kan eredi rẹ̀ ti o fi n yọ̀, tabi ki ni o pa á lẹrin. Nigba gbogbo ni Onigbagbọ le dahun wi pe alaafia Ọlọrun wà ninu ọkàn oun ati pe a ti mú awọn ẹ̀ṣẹ oun rekọja lọ. Idi pupọ miiran ni o wà ti a fi n ni ireti.

Ireti yii, alaafia yii, ati awọn ohun miiran ti a ti darukọ duro lori otitọ yii pe Kristi ti kú fun wa. O ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ ki a "le ni iye" ani ki a "le ni i lọpọlọpọ" (Johannu 10:10).

**Ijiya**

Peteru sọ nipa ijiya Kristi, "olõtọ fun awọn alaiṣõtọ, ki o le mu wa de ọdọ Ọlọrun. Orişirişi ijiya ni ó wà: irora ti ara ati ipọnju nipa ti ẹmi ati ipọnju ti ọpọlọ ori. Lorişirişi ọna ni Jesu jiya. O ni irora nipa ti ara nigba ti O sọrọ lori agbelebu. O ni ipọnju pupọ nipa ti ẹmi nigba ti Ọlọrun yí oju kuro lara Rẹ̀ (Matteu 27:46), nigba ti Peteru sẹ́ Ẹ (Marku 14:68-72), ati nigba ti O fi iwayá-ija gbadura ni Getsemane (Luku 22:44). Jesu jiya idanwò (Luku 4:2), ibanujẹ (Johannu 11:35), inunibini (Luku 4:28, 29), ati ọpọ nnkan miiran ki O ba le tu wá ninu (Heberu 2:18) ati ki O ba le fi apẹẹrẹ silẹ fun wa (1 Peteru 2:21).

**Awọn Iyiiriwo**

Lẹyin ti Peteru ti darukọ nnkan ti Kristi jiya fun wa, o n sọ fun awọn Onigbagbọ bi wọn yoo ti ṣe nigba ti wọn ba n jiya. Awọn miiran yoo ni "idanwò iná" ṣugbọn wọn ko ni lati ka a si ohun ajeji. Kaka bẹẹ, n ṣe ni o yẹ ki wọn yọ̀ pe Kristi ka wọn yẹ si ẹni ti a le yiiri wò. Jobu la iyiiriwo kọja o si wi pe, "Ṣugbọn on mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura" (Jobu 23:10).

Awọn Onigbagbọ yoo jiya inunibini. Ninu iwaasu ori-oke a kà bi eniyan ti ni lati ṣe nigba ti a ba fi ṣẹsin tabi a fi ṣe ẹlẹya nitori o jẹ́ Onigbagbọ. Jesu wi pe, "Ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o si fò fun ayọ̀: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun: bẽni nwọn sá ṣe inunibini si awọn wolĩ ti o ti mbẹ ṣaju nyin" (Matteu 5:12).

Ninu ayé ijiya pupọ ni o wà lorişirişi, iranlọwọ diẹ ni o si wà. Wo bi o ti yatọ to si ti Onigbagbọ ti a ṣeleri fun pe: "Bi awa ba farada, awa ó si ba a jọba" (2 Timoteu 2:12), ati pe bi a ba ba A jiya, a o ṣe wá logo pẹlu Rẹ̀ (Romu 8:17).

**Kikó Aniyan lé Jesu**

Peteru pari Ẹpisteli yii, tabi iwe yii, nipa kiki awọn Onigbagbọ laya lati maa ṣora ati lati maa gbadura: lati ṣọra nitori a ni ọta "bi kiniun ti nke ramuramu", o si n rin kaakiri o n wá ẹni ti oun yoo pajẹ. A ni lati kún fun adura nitori a ko le ṣalai ni iranwọ Oluwa lati jẹ́ ọmọ-ẹyin tootọ ati lati jẹ́ aṣẹgun ni kikún.

Nipa rirẹ ara wa silẹ niwaju Ọlọrun ati eniyan ẹlẹgbẹ wa, a mọ̀ pe ni akoko ti Ọlọrun, Oun yoo gbé wa ga. Nipa kikó aniyan wa le E, a o ri pe ifẹ Ọlọrun yoo fa ohun ti o dara ju lọ wá sinu igbesi-ayé wa yoo si pese wa silẹ fun Ọrun. "Ọlọrun ore-ọfẹ gbogbo, ti o ti pe nyin sinu ogo rẹ̀ ti ko nipẹkun ninu Kristi Jesu, nigbati ẹnyin ba ti jiya diẹ, On tikarãrẹ, yio si ṣe nyin li aṣepé, yio si fi ẹsẹ nyin mulẹ, yio fun nyin li agbara, yio fi idi nyin kalẹ"

**AWỌN IBEERE**

1. Ta ni kọ Ẹpisteli yii?
2. Ta ni a kọ ọ́ si?
3. Bawo ni Onigbagbọ́ ṣe ni lati maa huwa ni ile ti rẹ̀?
4. Iru ọṣọ wo ni i ṣe iyebiye niwaju Ọlọrun?
5. Bawo ni eniyan ṣe le ni ọṣọ yii?
6. Ki ni ireti?
7. Ta ni Jesu jiya fun?
8. Ki ni ṣe ti Onigbagbọ fi ni lati maa yọ̀ nigba ti a ba n ṣe inunibini si i?
9. Ki ni Ọlọrun yoo ṣe fun awọn wọnni ti o rẹ ara wọn silẹ niwaju Rẹ̀?
10. Ki ni ṣe ti eniyan ni lati kó aniyan rẹ̀ lé Jesu?